OWE

Dukia ti a fi eru kojọ, ko nmu kia di olowo

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arọfọ ti -:
ANỌYIN LOHUNBI-ỌMỌGE- IMARO
APÁ KẸTA
LATI OWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16, Bamgbose Street,
Postage Extra

VOL. II No. 54 WEDNESDAY JULY 9, — JULY 15 1958 KỌBỌ KAN (1d)

# Agbon fo omode 'KEKERE' kan ni agbari

Eko. **A** gbo irohin wipe omobinrin Adelebo k a n gbe omo re pon lo se igi ninu oko leti osa.

Nigbati o de i b ẹ, o ri awọn ọmọdekunrin ti wọn gun ori igi agbọn ti nwọn nka eso igi agbọn na.

O ke si w ọ n wipe ki w ọ n ṣe pẹlẹpẹlẹ nitori agbọn ko gbọdọ bọ lu on. Awọn ọmọde ti o nka agbọn na si dahun pe kosi ewu, nitori awọn ti ka agbọn ti wọn fẹ ka t a n, awọn mẹta ninu w ọ n si sọkalẹ, o wa ku ọkan loke.

Obinrin Adelebọ yi ti nwọn npe ni Christiana Iyabọ sọ ọmọ ẹhin rẹ kalẹ o gbe j o k o si abẹ igi agbọn. Lojiji ni odu agbọn kan ja loke, o si ba ọmọ kekere na ni agbari, o si fọọ yanyan. Nigbati nwọn ma gboju soke, nwọn ri ẹnikan ti o nsọkalẹ bọ lati ori igi agbọn.

Awọn Ọlọpa bere lọwọ gagbọn-gagbọn na w i p e Pantiwa? Gagbọn - gagbọn na si dahun wipe on nsọkalẹ bọ lati ori igi agbọn nigbati ẹsẹ on fi yọ, nibiti on gbe njijadu wipe ki on ma jalulẹ lati ori agbọn na ni agbọn kan ba ja lulẹ funra rẹ.

Adajọ rọ ọrọ na siwaju, sẹhin, o si pinnu wipe eṣi ni jamba na. Ọmọ ti agbọn fọ lori na ko ju ọmọ ọdun kan lọ. Orukọ si njẹ Okobokie Christmas. Lọwọ iku ojiji ati iku gbigbona, Oluwa rere gbawa.

## AKIYESI

Ẹniti o ba fẹ ra IROHIN IMỌLẸ ni Agege, ki o lọ si ọdọ AṢOJU wa ti orukọ rẹ njẹ ỌBANLA'S, tabi ni ile iṣẹ rẹ ni A D E ỌBANLA OFFICE

1/49 Lagos Motor Road
Isalẹ-Ọja

## PUBLIC NOTICE

No. 87

The Department of Co-operative Societies, Federal Territory of Lagos, has removed from Moloney Street to 147, Broad Street, Lagos (Third Floor Marina Entrance).

**Temporary Telephone, Number 25031.**



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni awọn elere idaraya ti o lọ lati ile Naijiria silu Oyinbo lati lọ ba won şere idaraya kefa eyiti nwon fe se nilu Cardiff ni ojọ 18th ati 26th osu July 1958 nigbati won gunlẹ si ilu oyinbo daradara- Ogoji enia ni gbogbo won ti o lọ nile yi. Awọn meji obinrin ti o je ọbi kanna wa ninu won-

## AFFIN-ORO TRANSPORT: (KIA-KIA BUS)

Mọto (Motor) wa yi ṣetan lati gbe ẹnikẹni de ilu rẹ. Koda boṣe ẹnikansoso lẹhingbati o bati wo inu ọkọ na.

### AWON ILU BI :-

| | |
|---|---|
| AJASE-PO | OKE-OLA |
| ILUDUN | OTTUN-ORO |
| ESIE | IJOMU |
| IDDO-ORO | OKERIMI |
| IBỌDE | AGBERUN |
| SANMỌRA | AFFIN-ORO |

Ẹnikẹni ti o ba fẹ san owo fun wiwọ ọkọ yi, ni lati san si Ile Iṣẹ:-
c/o Joseph Agboola; 60, Kosọkọ Street, P. O. Box 850, Lagos, Nigeria.

NỌMBA AWON MỌTO NA NI YI :-
NO. 1 LC 9776 NO. 2 LC 9780

## Egbe Olorunsogo Trading Company Oro

Eyi ni awọn ọjọ ti Motor yio ma kuro ni Eko.
MONDAY, WEDNESDAY, FRIDAY
Eyi dẹ ni ọjọ ti yio ma kuro ni Ọtun Oro
TUESDAY, THURSDAY, & SATURDAY
Tẹ ba fẹ wọ Motor yi ni Eko, ẹo lọ si:-
28 Idunmagbo Avenue c/o Mr- Michael O. Awoyale
Motor yi ko gba ju enia mẹtala lọ.

Agogo mẹsan owurọ ni Motor yi yio ma kuro ni Eko ati ni Ọtun Oro pẹlu.

Manager: M. O. AWOYALE

# Ori Wo Ibi're Gbemi Si, Ese Wo Ibire Sin Mi Re.

BI Olotu bale gbami laye inu mi yio dun. Mo juba J. O. Shoyinka onitan didun Oluwa yio ma ran Ogbeni na lowo amin ase.

Itan ti mo fe so yi dun pipo mo si fe ki awon ojogbon tete fun mi ni esi re.

Ori wo ibire gbemi si, Ese wo ibire sin mi re, ohun lo difa fun Oba ilu kan. Oba yi ni omobirin kan, olowo ilu fe omo Oba yi, ijoye ilu fe afeti ni.

Omo Oba yi so pe baba Alagbase ni on yio fe, o ni enia ti o ni ki on ma fe ko ni ku, ko ni sa, a ma gbe ile gbo.

Oba ba pe omo re wipe nigbati olowo ilu fe o ti iwo ko fe won iwo ati baba Alagbase ki e jade ni ilu, nitori emi ko fe ija ni ilu. Omo Oba ati baba Alagbase ba kuro ni ilu, nigbati won jade ti won de ehin ibode ni baba Alagbase ba daku, ni omo Oba ba beresi sokun, beni baba Olode kan ba yo si won ni okere ati omo re obinrin, ni baba olode ba bere lowo omo oba pe kini de ti o nsokun o si wipe baba Alagbase ti ohun fe ni o daku.

Baba olode ba ji baba Alagbase ni on yio fe, iyawo baba alagbase ba di meji. Baba Olode wa so fun won wipe ilu ti o wa ni iwaju won yan, enia ko gbodo wo ibe ni oru.

Awon meteta ba nlo won rin to ibuso mewa (10mls) ni ile ba su ba won, ni won ba wo ilu yan ni oru.

Bi won ti wo ibe ni awon ti nso ode bo mu won lo si ile oba ilu ibe, won wa so fun baba Alagbase wipe awon yio bere nkan meta bi o ba di ola, bi e ba mo meteta na, awon yio pa oba awon dipo baba Alagbase, bi iwo ko ba mo awa yio pa o, on ni olukuluku ba gba ona tire lo.

Omo oba ilu na wa ni omobirin o wa to baba Alagbase lo o ni se iwo yio fe mi, baba Alagbase so wipe on yio fe o, omobirin na wa so fun wipe nkan meta ti won yio bi o ni ola niyi, yara to wa ni owo otun eru Oba ni, iyara owo osi ofifo ni, iyara to wa ni okankan eru ilu lo wa nibe, omo Oba na wa so fun pe bi iwo ba ranti ohun gbogbo ti mo so fun e yan, bi iwo ko ba gbagbe won a pa oba dipo iwo baba Alagbase.

Iyawo baba Alagbase wa di meta. Bi ile ti mo gbogbo ilu ti pejo Oba papa gunwa, balogun ilu pe oba ilu le meta wipe se ki awon se ero ilu fun baba Alagbase, Oba dahun o ni ko buru o.

Balogun ba pe baba alagbase wipe Yara to iwa ni owo otun kini o wa nibe, baba alagbase so wipe eru Oba ni, o ni eyiti o wa ni okankan nko, baba alagbase tun wipe eru ilu ni, eyi to wa ni owo osi, ofifo ni.

Lati Owo:—
A. O. A. O. OYADOLA
Iludun.

Balogun yiju pada o be Oba l ri, o ba fi baba Alagbase je Oba ilu. O dagba o pe ipri oye, o tuu ilu se agbowo re kini bi iyawo omokunrin, ekeji na bi omokunrin, eketa na bi omokunrin.

Nigbati o pe Oba waja (ku)

Ibiti mo nlo ni mo de yi. MO FE KI ENYIN OJOGBON LAYE MI. Tani o ye ki won fi je OBA ninu awon omo iyawo meteta yi???

# BABA OLOMO META

INU mi yio dun pupo bi Olotu ba le gbami laye lati fi itan yi siwaju awon onkawe wa yi, itan mi na si tun ba Ibere lo

Itan mi na lo bayi:—

NI igba lailai, baba kan wa o bi omo meta, awon meteta na si je okunrin, oruko awon omo na nje:- Mudomudo. Meremere ati Lakutalakuta.

O wadi ni ojo kan, awon omoyi ati baba won wa lo si oko, gbogbo won wa nro ile gegebi agbe bena si ni won nko pelu, ise won na wa gba omi tobe gee. Nigbana ni baba won wa ni ki asiwo nisisiyi kia lo jeun ni abule wa.

Gbigbo ti awon omo yi

Lati Owo:—
Y. ADE. BURAIMOH
Omo-Otun-Oro.

gbo, jiju ni won ju oko won sile ti won sare lowa isu ti won yio je ni abule, bi won ti wa isu yi tan beni gbogbo won ba lo si abule won lati lo se eto atibu isu na ka ina, kia ma faa gun, won se eto tan patapata, isu fere jinna lori ina, ni baba won bani ki eni kan lo pon omi wa ninu won, gbogbo won si dake, kosi eni tio gbe agbe ninu won.

Baba ni se kowa si omode kankan ninu yin ni, tabi kini se tie fi nwo mi beyen? enikankan ko fo esi ninu awon omo meteta yi.

Nigba na ni baba won ba gbe akeregbe lati lo pon omi wa fun won mu, nigbati baba lo si odo tan, oto ki baba de baba ko de aya awon omo yi wanja pupo, kini se baba wa ti ko fi ti de lati ekan, okan ni boya odo gbe baba wa lo? okan ni omuwe ni baba wa je nigboro ilu wa, eketa ni tabi eja nla gbe baba wa mi ni? kia ma fa oro na gun, gbogbo won ba fi ona odo pon, alada mu ado, oloko mu oko, oni kumo mu kumo o di ona odo.

KO I TI PARI

THE COMRADES By Scorpio No. 36



"They're strong, dependable machines ...... Igor, bring the glue pot!"

FREEHOLD HOUSES FOR SALE
ITIRE ROAD ESTATE, SURU - LERE
NEWLY BUILT DETACHED FREEHOLD HOUSES
( THREE AND FOUR ROOMS )
Prices From £1,320
Over half this Estate has now been sold
Inspect Show House at Race Course
Reasonable Mortgage Terms arranged
FULL DETAILS FROM :
LAGOS EXECUTIVE DEVELOPMENT BOARD
( ESTATE DEPARTMENT )
Reclamation Road, Lagos Telephone 20384

